# Ọlọhun o nii gba irun ẹnikẹni ninu yin ti o ba ti ni ẹgbin lara titi ti yio fi ṣe aluwala

Lati ọdọ Abu Hurayra - ki Ọlọhun yọnu si i - lati ọdọ Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - o sọ pe: «Ọlọhun o nii gba irun ẹnikẹni ninu yin ti o ba ti ni ẹgbin lara titi ti yio fi ṣe aluwala».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe alaye pe dajudaju ninu awọn majẹmu nini alafia irun ni: Imọra, nitori naa o jẹ dandan fun ẹni ti o ba fẹ ki irun ki o ṣe aluwala ti o ba ṣe pe ọkan ninu awọn nkan ti o maa n ba aluwala jẹ ba ṣẹlẹ si i; gẹgẹ bii igbẹ tabi itọ tabi oorun tabi nkan ti o yatọ si i.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee